# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

## OṢÙ KẸ́WÀ, ỌDÚN 2024

**Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́**

## OṢÙ KẸ́WÀ 2024 – AGBÁRA GBỌ́DỌ̀ PÀRỌ̀ ỌWỌ́
## ÀWỌN ORIN ÌBẸ̀Ẹ̀RẸ̀

1. **Gbé Olúwa ga pẹ̀lú mi,**

Ẹ̀yin ènìyàn Rẹ,
Kí gbogbo ẹ̀dá alàyè,
Ma yọ̀ l'órúkọ Rẹ̀,
Fún ìfẹ́ tí Ó n fihàn,
Fún ìsinmi l'ọ́kàn wa,
Fún igbàlà kíkún Rẹ̀,
Tìrẹ lọpẹ́.

Kí gbogbo wa f'ọpẹ́ fun,
Kí gbogbo wa f'ọpẹ́ fun,
Kí gbogbo wa yin orúkọ,
Olúwa wa títí láíláí,
Àní, títí láíláí,
Kí gbogbo wa f'ọpẹ́ fun,
Kí gbogbo wa f'ọpẹ́ fun,
Kí gbogbo wa yin orúkọ,
Olúwa wa títí láíláí,
Àní, títí láíláí,

2. Ẹ̀yin fún ìwà-mímọ́ Rẹ,

Fún ore-ọ̀fẹ́ Rẹ,
Kọrin ìyìn fún ẹ̀jẹ̀ Rẹ,
Tó fi rà wá padà,
Ìfẹ́ ló fi wá wa rí,
Nínú ìrà ẹ̀sẹ̀ wa,

Ó f'ọ̀nà ìyè hàn wá,
Ẹ f'ọpẹ́ fun.

3. Èmí 'ba l'ẹ́gbẹ̀rún ahọ́n,
Nkò lè ròyìn ná tàn;
Ìfẹ́ Rẹ̀ sí mi pọ̀ jọjọ,
Ago 'bùkún mi nkún,
Ore-ọ̀fẹ́ tí kì yẹ́,
Àláfíà bí odò,
Lát'ọ́dọ̀ Olùbùkún;
Ẹ fọpẹ́ fun.

**1. Gbọ́! ìró lí òpópó ayé,**
Bí ti ìgbì omi òkun,
Tí nfi agbára rẹ̀ ru s'ókè,
T'ó sì nkọlu èbúté.

Gbọ́! bí ẹṣẹ̀ ọmọ ogun,
Bí wọ́n ti nrìn lọ lí ọ̀nà nà,
Àrẹ́ mú wọn fún 'sẹ́ àt'ìrìn àjò,
Àti ìjà kíkorò;
Ṣùgbọ́n wọ́n gbàgbọ́, wọ́n tẹjúmọ́
Ọ̀nà ná t'áwọn mímọ́ ti nrìn,
Bí wọ́n ti nlọ ní 'gbàgbọ́
Wọ́n ndàgbà n'nú Ọlọ́run alàyè

2. Wọ́n ntẹ̀síwájú pẹ̀lú ‘gbàgbọ́
Tí ẹ̀kọ́kẹ́kọ̀ kò lè mì;
Wọ́n gbàgbọ́ pé ọ̀rọ̀ Ọlọ́run
Lè pèsè f’áìní gbogbo.

3. Dàpọ̀ mọ́ wọn, àyéwà síbẹ̀
Dúró de ‘bùkún Ọlọ́run:
Òun ni ‘rètí gbogbo àgbáyé
Láti ṣiṣẹ́ òdodo.

## **ỌRỌ̀ AGBÁRA**

1. Níbo ni Olúwa Ọlọ́run Èlíjàh wà? Dìde, kí O sì dójúti ìtìjú mi lónìí, ní orúkọ Jésù.
2. Agbára òkùnkùn ìyówù, tó nkó ìbọ̀dè bá ìràwọ̀ mi, gbọ́ Ọ̀rọ̀ Olúwa, àrá iná Ọlọ́run yóò pa ọ́ run lónìí, ní orúkọ Jésù.
3. Ẹ̀yin agbára tí wọ́n yàn láti fi àwọn àlá mi dá ayànmọ́ mi lóró, Kìnìún ẹ̀yà Júdà yóò pa yín run lónìí, ní orúkọ Jésù.
4. Ìwọ aba àwọn ohunrere jẹ́ nílé bàbá mi, èmi kòlè jẹ́ ìjẹ rẹ mọ́, nítorí náà, gba ìdájọ́ Ọlọ́run Èlíjàh, kí o sì kú báyìí, ní orúkọ Jésù.
5. Ẹyẹ ibi tó nfò lòdì sí ayànmọ́ mi ni a ó já bọ́ lónìí, ní orúkọ Jésù.
6. Nípa agbára tó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, mo dúró lòdì sí gbogbo agbára ìbíntín, ìjákulẹ̀ àti ìdárungùn tí wọ́n yàn lòdì sí ayànmọ́ mi, ṣègbé báyìí, ní orúkọ Jésù.
7. Ọkùnrin alágbára ókúnkùn nínú ayé mi yóò kú lónìí, ní orúkọ Jésù.

## **ÀDÓ ỌRỌ̀ NÁÀ**

**Éfésù 3:20:** Njẹ́ ẹnití ó lè ṣe lọ́pọ̀lọpọ̀ ju gbogbo èyítí à mbèrè tàbí tí a nrò lọ, gẹ́gẹ́ bí agbára tí nṣiṣẹ́ nínú wa.

**Jeremíàh 29:11** Nítorí èmi mọ̀ ìrò tí mo rò sí nyín, li Olúwa wí, àní ìrò àláfíà, kì sí íṣe fún íbi, láti fún nyin ní ìgbà ìkẹyìn àti ìrètí.

**Deuterónómì 8:18:** Ṣùgbọ́n kí ìwọ kí ó rántí Olúwa Ọlọ́run rẹ, nítorípé Òn li Ó fún ọ lí agbára láti lí ọrọ̀, kí Òn kí Ó lè fi ìdí májẹ̀mú Rẹ tí O búra fún àwọn bàbá rẹ kalẹ̀, bí o ti rí lí òní yìí.

**Òwe 10:22:** Ibùkún Olúwa ní ímú ni ílà, kì íṣì ífi làlá pẹ̀lú rẹ̀.

**3 Jòhánnù 1:2:** Olùfẹ́, èmi n gbàdúrà pé nínú ohun gbogbo, kí ó lè ma dára fún ọ, kí o sì ma wà ní ìlera, àní bí ó ti dára fún ọkàn rẹ.

**Orin Dáfídì 1:1-3:** Ibùkún ni fún ọkùnrin nà tí kò rìn ní ìmọ̀ àwọn èniyàn búburú, tí kò dúró lí ọ̀nà àwọn ẹlẹ́ṣẹ̀, àti tí kò sì jókò ní ibùjókò àwọn ẹlẹ́gàn. Ṣùgbọ́n dídùn-inú rẹ̀ wá lì òfin Olúwa; àti nínú òfin rẹ̀ li ó nṣe àṣàrò lí ọ̀sán àti lí òru. Yóò sì dàbí igi tí a gbìn sí etí ipa òdò, tí nso èso rẹ̀ jáde lí àkokò rẹ̀; ewé rẹ̀ kì yóò sì rẹ̀; àti ohunkóhun tí ó ṣe ní yóò ma ṣe dédé.

**Òwe 3:9-10:** Fi ohun-ìní rẹ bọ̀wọ̀ fún Olúwa, àti láti inú gbogbo àkọ́bí ìbísí-oko rẹ̀. Bẹ́nì akà rẹ yóò kún fún ọpọ̀lọpọ̀, àti àgbá rẹ yóò sì kún fún ọtí-wáínì tuntun.

**<u>ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ</u>**

**ÌJẸ́WỌ́: ORIN DÁFÍDÌ 91**

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Àwọn agbára tí wọ́n n banújẹ́ nígbà tí wọ́n bá ri pé mò n tẹ̀síwájú, ìwọ àrá Ọlọ́run, pa wọ́n run báyìí, ní orúkọ Jésù.
4. Àwọn agbára òru tí wọ́n nkó àyídáyidà bá alàjá nípa ṣẹ̀ àlá, èmi kì íṣe èrò rẹ; kú, ní orúkọ Jésù.
5. Àwọn agbára tí wọ́n n pín orúkọ mi kiri fún ibi, ẹ rọ́pò mi nípa iná, ní orúkọ Jésù.
6. Àwọn agbára tọ́ n jàmílólè ohunrere, àkokò yín ti dópin; ẹ kú, ní orúkọ Jésù.
7. Àwọn agbára tí wọ́n ti fi ara wọn dá májẹ̀mú láti takò mí, ẹ já ìdè yín, kí ẹ sì kú, ní orúkọ Jésù.

**<u>ÒWÒ MI GBỌDỌ̀ ṢERERE / IṢẸ́ MI GBỌDỌ̀ ṢERERE</u>**

1. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ, Ọlọ́run, fún pípésè fún ìṣerere mi, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, fún mi ní ìfòróróyàn atòkèwá Rẹ láti ṣerere nínú owo/iṣẹ́, ní orúkọ Jésù.
3. Nínú òwò/iṣẹ́ mi, mo kọ̀ láti fọ́jú sí àwọn ànfàní atòkèwá mi, ní orúkọ Jésù.
4. Gbogbo òkúta tí wọ́n gbé sórí ìtẹ̀síwájú òwò/iṣẹ́ mi, túká, ní orúkọ Jésù.
5. Mo de ẹ̀mí òṣì ní gbogbo agbègbè ayé mi, ní orúkọ Jésù.
6. Níbo ni Olúwa Ọlọ́run Èlíjàh wà? Dìde, kí O sì ró òwò/iṣẹ́ mi lágbára fún àwọn àlàjá tíkòwọ́pọ̀, ní orúkọ Jésù.
7. Níbo ni Olúwa Ọlọ́run Èlíjàh wà? Mú òwò/iṣẹ́ mi tẹ̀síwájú nípa iná, ní orúkọ Jésù.

8. Ọlọ́run, dìde nípa agbára Rẹ, kí O sì la ọ̀nà fún òwò/iṣẹ́ mi níbi tí kò ti sọ́nà, ní orúkọ Jésù.
9. Ọlọ́run, dìde nípa agbára Rẹ, jẹ́ kí ìṣerere mi tíkòwọ́pọ̀ farahàn, ní orúkọ Jésù.
10. Gbogbo orí búburú tí wọ́n gbé dìde láti tẹrí òwò/iṣẹ́ mi ba, mo fà ọ́ lulẹ̀ nípa agbára Ọlọ́run Èlíjàh, ní orúkọ Jésù.
11. Bàbá mi, jẹ́ kí ọ̀run òwò/iṣẹ́ mi ṣí báyìí, ní orúkọ Jésù.
12. Ọlọ́run kòṣeuntì, ró òwò/iṣẹ́ mi lágbára gaju ìfẹ́ àwọn ọ̀tá mi lọ, ní orúkọ Jésù.
13. Bàbá mi, jẹ́ kí òjò àlàjá rọ̀ sórí òwò/iṣẹ́ mi, ní orúkọ Jésù.
14. Àwọn agbára tí wọ́n fí òórùn òdì sí àyíkà òwò/iṣẹ́ mi, lòdì sí àwọn ibùkún mi, já ìdè rẹ, kí o sì kú, ní orúkọ Jésù.
15. Gbogbo agbára àjèjì tí wọ́n yàn láti ti àwọn olùranlọ́wọ́ rere kúrò nínú òwò/iṣẹ́ mi, gba itìjú nípa iná, ní orúkọ Jésù.
16. Gbogbo agbára tó n gbé àwọn anfàní rere mìn, òwò/iṣẹ́ mi kì íṣe èrò rẹ, kú, ní orúkọ Jésù.
17. Àwọn agbára tí wọ́n n rúnú nígbàtí mo bá ti súnmọ́ alàjá mi, àkokò yín dópin lónìí, kú, ní orúkọ Jésù.
18. Àwọn agbára tó n yọ orúkọ àwọn ènìyàn kúrò nínú àkọsílẹ̀ orúkọ tó lérè, èmi kì íṣe ìjẹ yín, ẹ ṣubú lulẹ̀ kú, ní orúkọ Jésù.
19. Gbogbo agbára tó nfa rúdurúdu nígbàtí ó bá tó àkokò fún mi láti tàn, òpùrọ́ ni ọ́, ṣubú lulẹ̀, kí o kú, ní orúkọ Jésù.
20. Ohunkóhun nínú òwò/iṣẹ́ mi, tó n fọwọ́sowọ́pọ̀ pẹ̀lú àdánù nínú òwò, kú, ní orúkọ Jésù.
21. Gbogbo pẹpẹ búburú tí wọ́n yàn lòdì sí òwò/iṣẹ́ mi, gb’iná, ní orúkọ Jésù.